**Ọrẹ agba**

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

**Irohin Yoruba**

NO. 124 WEDNESDAY OCTOBER 7—TUESDAY OCTOBER 13 1964 KOBO MẸTA 3D

**Akiyesi**

'POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

# 'EBI NPA AWỌN OLUKỌ'



## 'Wọsẹwọsẹ yio wo iṣẹ Dọmọnu'

Igbe Awo! Awo!! Awo!!! gbode kankan ni ibi ipade ita gbangba kan ti Oloye Iyaafin H I D Awolowo ti ise iyawo babasalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ṣe pẹlu awọn enia ni ilu Odogbolu ni ile Ijẹbu ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kerindinlogbọn osu kẹsan ọdun yi nigbati Iyaafin Awolowo sọ pe kinnikinni ni Igbimọ iwadi yio tu gbogbo iṣẹ ẹgbẹ Dọmọnu wo ti ajumọsepọ ẹgbẹ itẹsiwaju orilẹede yi ba bori ninu idibo na ti o fẹrẹ de tan bayi si Ile Asofin Apapọ orileede yi.

Mọto akẹru nla marun ni o ko ogunlọgọ awọn obinrin lati Ibadan tẹle Iyafin Awolowo lo si ibi ipade na, Iyafin Awolowo se alaye pe igbimọ iwadi yi ni yio mu ki gbogbo aiye mọ dajudaju pe ọta awọn mẹkunnu gan an ni ẹgbẹ Dọmọnu iṣe, ati pe awọn enia diẹ ti ọwọ wọn ti to eti tẹlẹ ni ẹgbẹ na wa fun lati tẹ wọn lọrun.

Iyafin Awolowo so pe ki o to di pe ofin pajawiri gbode ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni owo ti o to ọkẹ marun pọnun (£100,000) ti wa nilẹ lati fun awọn enia ilu Odogbolu ni omi ẹrọ, ṣugbọn nigbati ofin pajawiri kasẹ nilẹ ni ipinlẹ na, eto lati fun awon enia na ni omi ero parẹ patapata di oni oloni.

O fikun pe ẹgbẹ Afẹnifẹre da ọda si gbogbo oju ọna moto, o si pese ina onimọnamọna fun awọn enia ilu na sugbọn ẹgbẹ Dọmọnu ko se rere kankan fun awọn enia ilu na yatọ si pe ki nwọn ma fi ẹrọfọ tun oju ọna moto ọlọda se.

Iyafin Awolọwọ fesun kan ẹgbẹ Dọmọnu pe ẹgbẹ na yan, awọn alatilẹhin rẹ ti ko gbajumọ rara gẹgẹbi aṣoju ninu awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ nigbati o jẹ pe awon enia ko ni ifẹ si wọn rara.

Iyafin Rafatu Obisesan ti o tun nje "Sisi Ghana" ti on na tun sọrọ ninu ipade na ṣe alaye pe Oloye Awolọwọ njiya nisisiyi nitori gbogbo mekunnu orilẹede yi.

O ni aiye nilati su enia lati ma gbe bi Oloye Awolọwọ ba wa lọgba ẹwọn sibẹsibẹ.

O wa rọ gbogbo awọn enia ni ilu Odogbolu lati duro gbọningbọnin lẹhin ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ọkan ninu awọn aṣoju ni Ile Igbimọ Asofin Iwọ Orun, Ọgbeni Solankẹ Ọnaṣanya sọ fun awọn enia ninu ipade na pe ki nwon mase gbagbọ pe nwọn ti yan ẹniti yio du aye Ijoko ti o wa fun agbegbe Gusu Iwọ Orun Ijẹbu.

O wa se alaye pe idibo na ti o nbọ yi ni yio jẹ anfani ikẹhin ati olubori

(Wo oju ewe kejọ)



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

## Iṣubu Ẹgbẹ Akintọla ku si dẹdẹ —Iya-abiye

Oloye (Iyaafin) Hannah Idowu Dideolu Awolọwọ, iyawo Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, babasalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre Naijiria ti kesi gbogbo awọn alatilẹhin ẹgbẹ itẹsiwaju Ọlọpẹ, Alakukọ ati Onirawọ (UPGA) lati duro gbọningbọnin fun Iwọnba asiko ti o ṣẹku fun ẹgbẹ Dọmọnu (NNDP) lati fi ṣe 'yanga' ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Iyaafin Awolọwọ lodi si ohun ti o pe ni iwa Ireniję ati ikorira ti ẹgbẹ Dọmọnu (NNDP) nhu si awọn enia Ipinlẹ yi nibi ipade kan ti o ṣe pẹlu ẹgbẹgbẹrun enia ni Eruwa ni agbegbe Ibarapa nitosi Ibadan ni ọjọ kẹta oṣu yi.

Iyaafin Awolọwọ kesi awọn enia lati dibo rẹpẹtẹ fun ẹgbẹ itẹsiwaju 'UPGA' nitoripe nipa didibo fun ẹgbẹ na ni o le da ominira Oloye Awolọwọ pada gẹgẹbi

(Wo oju ewe kejọ)

## Nwọn fọnmu mọ Ijọba lọwọ

GBOGBO awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ ni orilẹede yi ti ṣetan, nwọn si ti gbaradi nisisiyi lati lọwọ ninu idaṣẹsilẹ gbogbo awọn olukọ ti orilẹede yi ti o ti bẹrẹ lati ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kini oṣu yi.

Ni ọjọ Aiku ti ṣe ọjọ kẹrin oṣu yi, Igbimọ alabẹṣẹkele ti ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ (JAC) ti kilọ fun gbogbo awọn Ijọba Ipinlẹ ati Ijọba Apapọ orilẹede yi pe ti o ba jẹ pe edeaiyede ti o wa larin awọn ijọba na ati awọn olukọ orilẹede yi ko ba pari titi ti o fi di ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi, a jẹ wipe gbogbo awọn oṣiṣẹ orilẹede yi yoku na nilati da iṣẹ silẹ lati fi ẹdun ọkan wọn han fun awọn olukọ.

Ọkan ninu awọn alaga igbimọ na, Alhaji Haruna Adebọla sọ ninu iwe kan ti o kọ si Alakoso Ijọba Apapọ fun eto iṣẹ pe o jẹ ohun iwukan lati ri pe gbogbo iṣesi Ijọba Apapọ lori ọrọ na ko tilẹ mu ni doko rara".

Alhaji Adebọla sọ pe didá ti awọn olukọ na da iṣẹ silẹ jẹki awọn akẹko wa gẹgẹbi aguntan ti ko ni oluṣọ.

Alhaji Adebọla tẹsiwaju pe awọn olukọ ki iṣaba da iṣẹ silẹ tẹlẹ ri, o wa jẹ ohun ẹdun ọkan lati ri pe Ijọba Apapọ se ileri pẹlu akọsilẹ ti o ye koro lati tẹ awọn olukọ wọnyi lọrun, ṣugbọn ijọba na ko mu ileri na ṣẹ mọ, eyiti o mu ki awọn olukọ taku lati da iṣẹ silẹ kakiri orilẹede yi.

Igbimọ alabẹṣẹkele awọn oṣiṣẹ na sọ pe ohun ti awọn olukọ nja fun tọ suna, o si yẹ ki ijọba na gbọ ti won lai fa ọrọ gun lọ titi.

Ninu ọrọ tirẹ ni ọjọ Aiku

(Wo oju ewe kejọ)

## 'AWO YIO D'OLOTU'

OGBOKANGI kan ninu egbe Afenifere Naijiria, Oloye G.B.A Akinyede ti so asotele pe Oloye Obafemi Awolowo ni yio se Olotu Ijoba Apapo Naijiria ti o nbo yi, lehin idibo apapo.

Niwaju awon egbegberun awon enia ti o wa si bi ipade kan ti eka egbe odo Afenifere se ni Mushin ni irole ojo Ojobo ti ise ojo kini osu kewa odun yi ni o ti so oro na.

Ninu oro kukuru ti o so nibe, o so pe o je ohun ti o je ibanuje okan fun olukuluku lati ri pe awon enia ti ko jiya nitori ominira Naijiria ni o wa nje oro ibe loni.

Oloye Akinyede wa kesi awon enia lati fun egbe UPGA (Olope, Alakuko ati Onirawo) nisegun atata ninu idibo apapọ ti o nbo yi.

"Bi enyin ba nfe ki Awo tun pada lati wa tun je okan ninu awon ti yio tun Naijiria se, ki gbogbo okan le tun pada di mere mere nipa ogbon ati agbara, o ye ki gbogbo enia dibo fun egbe Olope, Alakuko ati Onirawọ.

# OLOTU MI ỌWỌN

## Dọmọnu de, arun de

Olotu,

Inu mi yio dun ti Olotu ba gba mi laye latiba mi te iwe mi yi jade lati fi kilo fun awon omo Yoruba lati yera fun egbe Domonu ninu ibo ti ao di laipeyi. Kini iwuri ti awon owora oselu egbe Domonu ti se? Nwon so Yoruba di eni egan ati yerepe.

Nwon nko ile kiri bi eiye nigbati awon talaka ko ri onje je:

Kini o ya enyin omo Ibadan lori mimu egbe okanjole? Bi e ba fe se egbe ko ha ye ki e ye awon olori re wo dada? Awon ti ko anfani fun ilu re bikose ara won nikan o wa le wulo fun yin ati orilede wa bi?

Oluwa ko ni jeki awon Hausa ati awon aja won bori ninu ibo ti a o di: Kini yio sele bi awon sugonu ba gba ijoba? Isẹ, anu ati aimokan wo orileede yi nuun, Oduduwa ko ni fun ẹgbẹ Olọmi se o.

Ẹ dibo fun ẹgbẹ Ọlọpẹ ati Alakukọ, ki igbesi aiye nyin ati ti awon omo nyin ko le dara. Oluwa ko ni jeki ẹ bi arọ omo, ẹ wo orisirisi arun ti nwon berẹ si ko wọ Ilu nigbati wọn dẹru Sannu, ẹjeki a fi ibo le wọn ati arun won lo.

Awon oponu wa nkigbe pe awon ko ba awon Ibo ṣe nisisiyi. Nwon ti gbagbe Ija igboro Kano ni ọdun 1948 ti awon Hausa fẹ pa Ibo ati Yoruba rẹ.

Tani Olugbala Yoruba ni asiko yi, ki ise Ibo ni? Olore ẹnyin ọdalẹ odo Oya ni yio gbe lọ. Kini arukọ ẹgbẹ nyin? Wobia parapo.

Ẹniti o ba ti ibi ida pani ibi ida ni yio ti ti subu gbogbo awon alaise ti ẹ ti fi ara ni ki ẹ mase sun asunnara o.

Ni ipari mo kesi gbogbọ awa omo Yoruba gidi lati ra iyi wa ti nwon ti gbe sonu pada nipa didibo fun ẹgbẹ Alakuko, Ọlọpẹ ati itẹsiwaju gbogbo,

Emi ni

Ọjọyẹ Ọmo Okebadan
Ibadan




## T'agba t'ewe fẹ ri Awo

Ẹjọwọ Olotu ẹ maṣẹ binu wipe odi igba gbogbo mi Bi aiye ba yipada ti odi orun, Ifẹ mi si ẹgbẹ Afẹnifẹre ko le yi. Adura mi ni wipe ki Ọlorun fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ni iṣegun ninu ibo ti mbọ yi.

Ọpẹ ni fun ẹgbẹ Afẹnifẹre fun obinrin atata obinrin bi okunrin ti Ọlọrun fi ta Oloye Ọbafemi Awolowo lọrẹ. Ibẹwo ti Iya-Afin Awolọwọ ṣe yika Ipinle yi ko ni saidun mọ gbogbo ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu.

Ibẹwo na ba itan iṣelu dọgba. Ohun ti o de ba ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ ti sele kakiri agbaiye, ayo ni o si ngbehin re. Ṣe awa na mo wipe adun ni gbehin ewuro.

Mo tun ngba Iya afin Awolowo niyanju lati se Iru ibewo be yika Naijiria. Awon enia fi ijo iyi, eye ati idunnu pade Iya-Afin Awolowo.

Bi ale yio ba ti ri, owuro ni a ti nmọ' Iru ayeye, ijo, iyi at idunnu yi fihan wipe Isegun yio je ti Afenifere. Mo tun kesi Iya-Afin Awolowo lati fi ese kan de agbegbe Okeho ati Iganna nibiti iyi ati ogo yio ti je tiwon.

Gbogbo enia ni o ti ri oju oro bayi. Ṣe enikan ninu egbe Domonu na se ibewo. Gbogbo ibi ti on na si de ni igo, o'cuta ati biriki di eiye ti o nfo ni oju orun. Gbogbo ibiti alafia ati idera wa ni arabinrin na tun lo da rukerudo sile nibe. 'Kokoro wo inu obi, o baje JAGUNLABI de Inu owo, owo parun'. Ẹgbe Domonu npuro kiri wipe awon omo egbe Afenifere Okeho ati Iganna di tiwon, erin pa mi titi.

Goọningbọnin ni aduro lehin Oloye Awolọwọ a ko si ko lati baa ku. Awa ko ri da ile nitori eniti o ba di ile yio ba ile lo.

Nipari oro mi mo kesi gbogbo awa ti ao dibo lati dibo fun egbe Afenifere ati Alakuko Ẹgbe mejeji yi nlo le se awọn nkan ti a nfe fun wa. Ki a mase lọwọ ninu iwa janduku egbe Domonu, ki a ranti wipe nigbati egbe Afenifere fi wa ni ijoba, aiye ri oju, oja ta, owo wa lowo gbogbo enia, awon oba si niyi gidigidi. Ki ẹ wa fi akoko na we akoko ti egbe NNDP.

Ọ. ADE, SUNMỌNU
Iganna.

### Gbon aisan awo ara re nu

Majẹ ki osu ẹ, tabi ki odamu popọ, larin ọjọ meji awọn oju, bi Ekuru, Alefo, Rorẹ, Awọn alebu ara miran, Ara sisu, Ara jijoni, Ara Itani, Arunkarun ti ole ma bi enia ninu ninu awọ ara, Lapalapa, Owo Imu, E-ela Oloronto, awọn orişirişi kokoro bi Jẹrunjẹrun, Kayun, ati Işaka Ẹsẹ. Yara lọdan NIXODERM ti afi ọgbọn ijilẹ popọ. Ọna mẹrin lofi nşe işẹ iyanu fun enia, Ara didẹ' Ara mimọ, Ara didan 1. (Ọna kini) NIXODERM nyara gbogun ti awọn arun bi ki Ara majanije, Kuruna, Ara sisu, Ara hihun ni; ti ole mu ki enia mafi ekan họ ara nigba-gbogbo, 2. (Ọna keji) NIXODERM ma npa awọn arun ti oma nda enia lamu ni ara, tabi ni oju, bi Rorẹ, Ifo, tabi Işaka. 3. (Ọna kẹta) NIXODERM Ma nle awọn nkan ti o ma nfa Alebu ara lọ. 4. (Ọna kẹrin) NIXODERM nşe iranlọwọ fun ara didan, Ara didẹ ati ki Ara madagbogbo enia lọrun. Lọ ra NIXODERM lọdọ awọn ti nta Egbogi ladugbo rẹ loni.

**Sincere Greetings**

**TO THE**

**Governments and people of Nigeria on the happy occasion of the First Anniversary of the Federation of Nigeria becoming a Republic**

*from*

**LEVENTIS**

**C·F·A·O·**

*GENERAL IMPORT*
*GARAGE*
*QUALITEX*
*ELECTRO HALL*
*PRODUCE*
*IBADAN.*

**Congratulates the Government and the people of Nigeria on the occasion of the Fourth Anniversary of INDEPENDENCE and First Anniversary of adopting A REPUBLICAN Status.**

**P. O. BOX 7,**
**IBADAN.**
**TEL. 24546|7**

